## Akiyesi

A nfẹ awọn enia ti yio ma ba wa ta Irohin Imọlẹ ni awọn ilu won-yi: Igbo-Ora Shaki Iseyin Erumu Lalupọ Akure-Ondo Ado-Ekiti Ogbomosho Ede Oyo Ede Ikorodu Shagamu Iloro ati Ilorin.

E kowe si:-
Olotu IROHIN IMOLE
16 Bamgbose Street
Lagos.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

## AKIYESI PATAKI

Ope nina awọn Onkawe wa si wa gbo, a ko si wipe a nfẹ Aṣoju lati ilu kan lo si ilu keji.

Ohun ti a wi gan ni wipe, a nfẹ Aṣoju ti o ngbe awọn ilu awọn lati ma ta iwe IROHIN IMOLE ni ilu na ki o si ma yo ere ori re, ki o si foju owo ranse. Abeokuta Ijebu-Ode, Akure, Ikorodu, Shagamu, Ede, Ilfa, Oshogbo, Ilorin, Okuku

VOL. VI No. 335 MONDAY JULY 2 — JULY 8 1962 KOBO MEJI (2d)


# BABA KAN FUN ỌMỌ RẸ LOYUN

SAPẸLẸ:— AWỌN ỌLAPA MU Ọ D A R A N KAN. WALKER SEGBA WA SI IWAJU ADAJỌ KỌTU KAN NI SAPẸLẸ FUN ẸSUN WIPE O FUN ỌMỌ RẸ OBINRIN FELICIA EDEMA ẸNI ỌDUN MEJILA LOYUN.

Ẹjọ ti Felicia ọmọ baba na ro niwaju A d a j ọ ni wipe, nigbati Iya on ko si nile ni baba on ba pe on ti o si sọ fun on wipe ki on wa na, Nigbati on si de ọdọ rẹ, o bi on lere bi on ba ti mọ Ọkunrin tabi on ko mọ Ọkunrin, nigbati on ko da a lohun ni o ba sọ wipe ki on bọra silẹ ni o ba gbe on si ori bẹdi ti o si ba on lopọ.

Felicia ko tilẹ tiju rara lati sọ wipe baba on tun pe on ni ọjọ keji wipe ki on wa sun ni ọdọ on, nigbati on si sun ti baba on titi ilẹ fi mọ ni baba on fi nba on lopọ.

Baba on si bẹrẹsi ba on lopọ lemọlemọ lẹhin eyi, titi ti on fi loyun on ko mọ rara, Ṣugbọn on ṣe akiyesi wipe o ma nrẹ on pupọ ju ati wipe inu a si ma run on.

Nigbati on si sọ fun baba on o fun on ni egbogi oyinbo kan lo, ṣugbọn ko din ohun ti nṣe on ku rara.

Awọn Ọlọpa ti fi Baba ọmọ na Walker si itimọle nwọn si ti fi ọmọ rẹ Felicia silẹ ki o ma a lọ si ile.

Bi ẹjọ na ba ti nlọ si ẹ o ma gbọ.

Ẹjọ ti Ọgbẹni Patrick Nkenchor ti ro mọ ọdaran na lẹsẹ niwaju adajọ wipe, ni oṣu keji ọdun yi, ni ọdaran na haya mọto ti awọn si jijọ wọ mọto na lọ si Asaba lati Ughelli nigbati on si fẹ s ọ k a l ẹ ni on ba wa ẹni ati agborun ti, on ko si ri i nigbati on si ri lọwọ ọdaran na ni o ba sọ fun on pe ẹgbọn on lo ni nigbati nwọn bere lọwọ rẹ pe nibo ni ẹgbọn rẹ to ni wa kole fun wọn ni ẹsi kan pataki ni adajọ ba fi ṣe idajọ gẹgẹbi a ti wi siwaju.

## Ẹniti o ji Ẹni ati Agborun wẹwọn oṣu mẹta

UGHELI:— Ọgbẹni O. Akensua, Adajọ Kọtu Ughelli, ṣe idajọ wipe ki Ọdaran kan Augustine Okah lọ si ẹwọn oṣu mẹta nitori pe o jẹbi ẹsun olẹ jija.

## "Woli" kan gbadajọ Iku

ONDO:— Kotu giga julọ Ondo kun ṣọṣọ fun ero ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandilọgbọn oṣu ti o kọja yi nigbati awọn Ọlọpa mu ọdaran kan, Ṣegun Wogbiren ẹni ọdun mejilelogun wa si iwaju Adajọ agba Kotu na Ọgbẹni Akin Delumọ.

Ẹsun ti awọn Ọlọpa ti o mu ọdaran na ro mọ ọ ni pe, ni ọ j ọ kọkandinlogun oṣu kẹjọ ọdun ti o kọja yi ni Ọdaran na mu obinrin aboyun kan Funmilayọ Ose ẹni ọgbọn ọdun ti o nrọbi lọ si ibikan, ti o si sọ fun un wipe, "Woli" ni on, on yio gbadura fun un ki o le ba bimọ ni alafia. Nigbati nwọn si de ibẹ, ni ọdaran na ba dumbu obinrin aboyun na bi ẹran Ileya

Nigbati ọdaran na a t i olu-ran-lọwọ rẹ Buramoh Otokiti rojọ ti nwọn si gba wipe awọn jẹbi ẹ s u n ti awọn Ọlọpa mu awọn fun ni A d a j ọ ba sọ wipe ki nwọn lọ yẹgi fun a w ọ n mejeji.


## IKEDE PATAKI

Eyi ni lati kede fun gbogbo ẹnyin Onkawe wa wipe awọn ỌJỌ OJA ILẸ wa yio b ẹ r ẹ si ma a jade ninu "IWE IROHIN IMỌLẸ" lati ọsẹ ti mbọ yi.

Ẹnyin Onisowo ati Arinrinajo jake-jado Ilẹ Yoruba, anfani nla-nla ni eyi. Tete ranṣẹ fun "IWE IROHIN IMỌLẸ" fun ọsẹ ti mbọ ki ẹ ma ba a kabamọ. Kọbọ meji pere ni.

OLOTU

## STAR LAGER

OFF - LICENCE SELLING PRICES

STAR large size bottle ... 2/9
STAR small size bottle ... 1/7

Selling price at Bars, Hotels and other on - licence premises

STAR large size bottle ... 3/-
STAR small size bottle ... 1/9

# Ọba Adeniji Adele gba Oye K. C. M. G.



Ọlọla Gomina Agba Dọkita Nnamdi Asikiwe fi oye nla K. C. M. G. da Ọba Alaiyeluwa Adeniji Adele keji lọla ninu ile Gomina ni ebute mọgasim ẹniti nwọn tun da lọla oye nla D. M. G. ni Oyinbo Ọlọpa ti o njẹ Kodge awọn enia nwọnyi ni Gomina Agba tun fi oye O. B. E. da lọla awọn ni Ogbẹni T. A. Williams ati T. E. A. Salubi.

Gomina Agba na ni a nwo ninu aworan yi nigbati o fi oye na si ara aṣọ Ọba Adele keji.

# Turari Itaja ati Ẹyọnu Agba

Ogun ti o jẹ ju Turari Ajẹbidan lọ ko si lasiko yi, Iwọ ba ti ra ninu Turari Ajẹbidan yi ri Iṣẹ pupọ ni turari yi nṣe, nipa lilo rẹ, (1) O nle aita Oja jinna si awọn onişowo, bi ogunguu pe Igba ninu agbọ, Ologbojo ni ọba wọn onişowo ti o ba nlo okuta ko ni ba. (2) Turari Adura gidi hanun ni, o ba jẹ Ima'e tabi Igbagbọ ti o ba ngba ekanṣe adura ma a lo o Ki adura rẹ le gba.

O tun wa bakanna fun ẹyọnu awọn Agba, nipa lilo rẹ awọn Agbalagba ati emi okunkun ko ni lagbara lori rẹ chunkohun ti o ba dawọle yio ma a lọ dede maṣe dẹja ra tirẹ loni ki o si danwo.

Pangolo 10/6d Idaji 5/6d

Manager, 6, Ojo Road
Odu Abọrẹ Mushin

# Yẹyẹnatu!

## ONI YẸYẸ EKO

Olotu:— Obinrin mẹta, Yẹyus-natus.
Yẹyẹnatu:— Ewo tun ni yẹn o?
Olotu.— Ṣe bi o ni o gboyinbo ni?
Yẹyẹnatu:— Wọyọ-wọyọ lẹ fọ hun ki ṣe oyinbo kẹ.
Olotu:— Ẹ ma ku isimi ana
Yẹyẹnatu:— Ẹ ku ipamọ t ọ j ọ meje A! hẹn! njẹ ẹ ri f ọ t o obinrin to yọ ninu Sọnde Taimus ijẹsan?
Olotu:— Fọto obinrin pọ nbẹ kẹ, ewo lo nwi?
Yẹyẹnatu:— Eyiti o wa ni ihoriho.
Olotu:— Ha! ha! Mo ri i, Mo tilẹ ni ki nso fun ọ ki o ma m u r a bẹ
Yẹyẹnatu:— Họwu, nitori kini?
Olotu:— Ha! ha! aṣọ asiko ni yẹn kẹ.
Yẹyẹnatu:— Aṣọ asiko ni ki obinrin wa ni ihoriho nilu ti Ọba wa
Olotu:— Ha! Yẹyẹnatu, aṣe o ko laju
Yẹyẹnatu:— Bẹni nko foju, Sa.
Ṣe ẹnyin le gba ki Iyawo nyin ma [illegible]rin ihoriho?



Olotu:— Hẹn! were dun wo kẹ. ko ṣe bi lọmọ ni.
Yẹyẹnatu:— O-ho, dats raiti. O ye mi wayi
Olotu:- Iyẹn ni pe o ko le ṣe Mis Naijiria?
Yẹyẹnatu:— Bawo?
Olotu:— A ni o ko mọ nkan to nlọ.
Yẹyẹnatu:— Ṣe loju i t i t i? Enia ati mọto ni kẹ
Olotu:— O de ko ma bẹ ase rẹ niyẹn
Yẹyẹnatu:— Pẹlu ọbẹ ni tabi ida?
Olotu:— Iyẹn ni pe o ko mọ bi wọn ṣe nṣe Mis Naijiria?
Yẹyẹnatu:- Ntori nko le tori ohunkohun rin ihoriho l o j u gbogbo aiye.
Olotu:- Lori owo ni kẹ.
Yẹyẹnatu:- Ha! hẹn! ntori na lo ṣe jẹ kofo lo nṣe ẹ.
Olotu:- Irọ o, aburo mi to ba wọn ṣe e nijelo o nṣişẹ oṣu.
Yẹyẹnatu:— Ha! ha! ha! Ntorina nkọ? Iyẹn ko ni ko le ṣe kofo kẹ. Orişirişi k o f o lo wa Ọmọ ile-iwe kofo wa Abilekọ kofo wa. A w ọ n ti o ngbegba asẹwo kiri gan nikan lẹyin npe ni kofo nī? Ha! am sọri pupọ.
Olotu:- Nkan ti mo mọ ṣa ni aburo mi ki ṣe kofo.
Yẹyẹnatu:- Kini ki ẹ wi? Titilọla na ki ṣe kofo
Olotu:- Ṣe ẹgbọn rẹ
Yẹyẹnatu:- Hẹn.
Olotu:- Ha! ha! ha! Yẹyenatu oni yẹyẹ. Titilọla ti g b o g b o enia mọ ni kofo
Yẹyẹnatu:- Ṣe bi nşişẹ
Olotu:— Hẹn! ṣe bi lalẹ lo nṣe kofo
Yẹyẹnatu:— Ha! hẹn! ṣe bi lalẹ laburo ti nyin na nṣe kofo
Olotu:— Rara, gbẹnu rẹ sọhun
Yẹyẹnatu:— Ija ni, bo ṣe nri ni yẹn.
Ọmọ ọlọmọ dun bu. E sa ti sọ pe w e r e dun wo.
O dabọ o.

# Ẹyin Obi, ẹ ma ṣe fi ikọkukọ kọ awọn ọmọ nyin

Ijẹbu-Ode:- Irohin yi wa lati igboro ilu Ijẹbu-Ode wipe awọn ọmobinrin mesan ninu awọn ọmọ ti Obi wọn fi si abẹ itọju ile ẹkọ giga kan ti a npe ni Our Lady of Apostles ba awọn ọmọde-kunrin kẹgbẹ lọ si ode oru lati lọ wo iran ere Sinima, laigba aṣẹ lọdọ ọga wọn.

Nigbati awọn ọmọbirin nwọnyi pada de, ile ti su pupọ, gbogbo enia ti sun ilẹkun ọgba ti ti, Iyalẹnu lo jẹ fun Olukọ agba, eyi ni Padi obinrin tişe alaşẹ wọn. Nigbati ilẹ mọ, Padi olukọ agba na le wọn jade pe ki wọn lọ gbe ile wọn fun ọsẹ mẹta, ki wọn r'aye lọ woran ere Sinima ki o si tẹ wọn lọrun

(E. D ) Ohun ti awa fẹ sọ ni wipe, ko nṣe ohun ti o tọ ki awọn Obi ma gba ọmọ wọn laye lati ma ba ọkunrin kẹgbẹ, ni şişe bayi, wọn ko ni le kọ ẹkọ nwọn dori.

# IFẸ LOJU (APA KEJILA)

LATI ỌWỌ Afolabi Olabimtan

Ibiti mo ba Itan mi yi de ni ọsẹ tokọja ni ibiti Iya Muli ti pinnu lati ṣe ogbogi Ifẹran gbigbona fun Muli ki o fun Ọkọ rẹ jẹ.

Nigbati Iya Muli ri Onisẹgun atata, o ba sọrọ. Iyẹn si gba lati ṣe iṣẹ Ibi na fun. Lẹhin eyi ni o pe Muli ti o si sọ fun. Ẹru ba Muli, ẹnu si ya pe Iya on nfẹ ṣe iru nkan bẹ fun on, ṣugbọn gẹgẹbi Ifẹ ti o ni si Ọkọ rẹ, o ro wipe ti on ba kọ loju Iya on, o le lọ ṣe ohun to buru si Ọkọ on to on ko si ni mọ. Ka ma fa ọrọ gun, Muli gba afunjẹ ogun Ifẹ lọwọ Iya rẹ, o si sọnu, o lẹran ti mu Ojogẹ. Iya rẹ kan sara si, o si ki dada, nitori ohun ti Muli ṣe yi, o fi opin si lati ma ro ẹjọ Ọkọ rẹ fun Iya rẹ. Ojogẹ papa ko si fi igba kan fẹran ẹjọ riro. Nipa bayi, Inu Iya yi ndun, o si pada lọ si ọdọ Onisẹgun, o ni "EWE NJẸ"

Lẹhin igbati nwọn ti pari Ija Muli pẹlu Ọkọ rẹ, Muli .i tun nta ọja rẹ lọ, o si njere pupọ lori rẹ bi ti atẹhin wa, ọpọlọpọ igba ti o ba si ra ohun kan pẹlu owo ara rẹ, A ni Ọkọ on lo fun on lowo. Eyi ko jẹ ki Iya Muli tun mọ otitọ nipa Ojogẹ pẹlu Aya rẹ, ko pọ lẹhin eyi Iya Muli ku. Oku Ọlọmọ gẹgẹ ni gbogbo ilu gbe, Ojogẹ pẹlu Iyawo rẹ na owo pupọ, T'onile talejo si mọ pe Oku Olowo, Oku Ọlọmọ ni nwọn sin ni ni akoko na! Lẹhin isinku yi, nwọn pin Ogun, eyiti o si kan Muli pọ diẹ.

Ni ọdun ti Iya yi ku, ni Muli bi Iyabọde, eniti o sọ lorukọ ni iranti Iya rẹ to di ologbe. Ẹru ti Iya Muli fi silẹ fun pọ tobẹ gẹ to fi jẹ pe nigbati o fi tirẹ kun o di Olowo; o di Ọlọla. Bo si ti jẹ pe Ifẹ atata ni o ni si Ọkọ rẹ, o fi Ọla na ran on na, gbogbo wọn si ngbadun.

Ni akoko yi, Muli kọ Ile-Itaja nla, o si ko ẹru to ju apo owo marun sinu rẹ, Inu Ojogẹ dun pupọ, Anu si ṣe ni pe Muli si Ile-Itaja nla ni ẹhin Iya rẹ, bi o tilẹ jẹ pe, ki iru ohun bayi ba ṣe ni o ṣe da ruke-rudo sarin Ojogẹ pẹlu Iyawo rẹ ni ọpọlọpọ igba, ṣugbọn ni idakeji ẹwẹ boya ni Muli iba tete si ti Iya rẹ ko ba ku, pẹlu owo yi Ojogẹ ati aya rẹ nto ọmọ wọn, nwọn ngbọ bukata owo nwọle. Nwọn di Ọlọla, nwọn di Onile, Ọlọna, gbogbo Ilu si mọ nwọn.

AKIYESI:— Lọsẹ to mbọ lagbara Oduduwa ẹ o ma gbọ ohun ti Baba Muli ṣe nigbati o ri pe ọmọ rẹ di Ọlọla ati Olokiki? O digba kan na o.

## Dokita Nnamdi Asikiwe da kan fo pada wa si ile, ṣugbọn — — — — —



Ẹniti a nwo yi ti nwọn ga Agborun le lori ni Ọlọla Dokita Nnamdi Asikiwe Gomina Agba fun ilẹ Naijiria nigbati o bọ silẹ ninu ọkọ Ofurufu ni Ikẹja lati ilu rẹ ni Nsukka ti o da kan wa si Eko lati lọ si ilu Kaduna fun Ibura ifi jẹ oye Gomina ilẹ Ariwa ti wọn fi Ọlọla Ibrahim Kashim jẹ nipari oṣu tokọja, Asikiwe ni a nwo ti o mbọ pẹlu Iyawo rẹ Mrs Asikiwe.

A gbọ pe, o si ti tun pada lọ si ilu rẹ nisisiyi nigbati o kuro ni Kaduna nitori koiti pari akoko isimi rẹ tan.

## Ibere pataki lọwọ awọn Agbalagba Ọnkawe wa

Mo nfẹ ki awọn agbalagba lọkunrin ati lobinrin fun mi ni imoran daradara nipa awọn ibere nwọnyi:-

(1) Eṣe bi Ọkunrin ba fẹ iyawo si ọna, ti nwọn yio ni ọpọlọpọ ifẹ si ara wọn, ti o si jẹ pe ti wọn ko ba ri ara nwọn ni ọjọ kan wọn ko iti le sun ti ife na yio pọ to bẹ ti obi nwọn ba ni wọn ko gbọdọ fẹ ara nwọn, wọn ko ni gba bi wọn ba wọ ile ara wọn tan, (ti nwọn di tọkọ taya) Ifẹ na yio wa din ku nwọn ko si ni fẹran ara nwọn to ti atẹhin wa.

(2) Mo fẹ mọ boya ọwọ ọkọ ni tabi ọwọ iyawo ni o ti nwa ati idi ti o fi jẹ ọwọ enitohun.

Kọ ki o si fi ranṣẹ si

Olotọ Obinrin
c/o Olotu Irohin Imọlẹ
16 Bamgboṣe street
Lagos

## Awọn Jamani ranṣẹ pe Ọgbẹni Hogan Bassey ko wa

Awọn Ẹgbẹ Abẹṣẹ kun bi ojo ti Ilu Republic ti Jamani ti orukọ wọn njẹ (German Amateur Boxing Association) ran aṣoju wọn ti o mbẹ nilẹ Naijiria Ọgbẹni Herman Krause wipe ki o lọ ri awọn enia meji wọnyi Ọgbẹni Hogan Bassey ati Ọgbẹni Jẹgẹdẹ wipe ki wọn wa bẹ Ilu Fedral Republic of Jamani wo ni ibẹrẹ oṣu July ki a ba le mu okun ere ẹṣẹ le larin ilẹ wa ati ti wọn.

Nigbati wọn si fi ọrọ na lọ awọn Olori Abẹṣẹ kun bi ojo mejeji na wọn si gba lati lọ fi oju kan Ilu na.

Ohun pataki ti a gbọ pe wọn titori rẹ pe awọn Omuṣa meji nina ere ẹṣẹ awọnyi fun ni wipe Ọkunrin Abẹṣẹ kun bi ojo kan ti o tobi ti o si nleri pe ko si iru on, ni gbogbo aiye ti orukọ rẹ njẹ Max Schmeling ni awọn fẹ ki Hogan Bassey ati Jẹgẹdẹ wa ba wọn pa lẹnu mọ.

# Ẹ MA FINU HAN OBIRIN NITORIPE OBIRIN NI O NPA NI O.

Lati owo:- Kolawole Idosu NO. 191, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLE AIYE

Itan kekere ti ma sọ yi yio fi han nyin gbangba pe Obinrin ko ṣe finu han, o si tilẹ dara l a i y e aiye, ṣugbọn obinrin Iwoyi awọn afani-lori-fọda-ku le kun inu aiye de ẹnu, ko tilẹ si eyiti o nṣe anu ẹni ninu wọn mọ, a fi eyiti yio da Oluwarẹ ni gbese ti yio si sa pada. Itan na lọ bayi:—

Nigba kan Ọkunrin kan wa ti oruko rẹ njẹ Salimọnu, o si ni Iyawo kan pẹlu, ṣugbọn akuṣẹ ni awọn mejeji, nwọn kuṣẹ tobẹ ge to je wipe nigbati ebi fẹrẹ fọ wọn loju ni eyi Ọkọ pinnu lati ma pa ẹja ati pe ẹja ti on ba pa ki Iyawo on ba on ma ta wọn, nipa bẹ awọn yio ma ri owo ra nkan miran ti o ba w u n awọn. Lotọ wọn bẹrẹ si nṣe bẹ, nwọn si ṣe fun ọjọ pipẹ. Ṣugbọn Ọba igbana jẹ Ọba ti o buru gan, o si ti pinnu lati pa Ọkunrin ti o njẹ Salumọnu yi, nipa bẹ o ranṣẹ si lowurọ ọjọ kan, Iyẹn na si lọ nigbati o de ọhun, Ọ b a na fun ni Oruka Golu kan dani pe ki o ba on mu dani fun ọsẹ meji. Lẹhin ọsẹ m e j i na on yio si gba pada ni ọwọ rẹ, on yio si tun fun ni ẹbun pẹlu, ṣugbọn ti ko ba mu fun on, pipa ni on yio pa danu.

Ọkunrin yi fi han Iyawo rẹ nigbati o de ile, o si tun ṣe alaye ohun ti Ọba wi fun. Inu Iyawo rẹ yi dun pupọ, nwọn si jijọ tọju rẹ sibikan ninu iyara nwọn, ṣugbọn ni ọ j ọ keji ni Ọba tun pe Iyawo Ọkunrin adẹja yi lẹhin ti o si bẹ pe ti o ba le ba on mu Oruka ti on mu fun Ọkọ rẹ wa, inu on yio dun to bẹ ti on yio da lẹla on yio si tun fun ni ẹgbẹrun apo owo. Inu obinrin yi dun tobe ti o ba Ọba se adehun pe on yio mu wa fun Ọba ni irọlẹ ọjọ na. Ha! ẹnyin obinrin ti ẹ ba ti ri o w o, ohun gbogbo ma ti t a n ni yẹn kẹ, ẹ ki ntun wẹhin wo mọ, eyi ko dara o, ile aiye ni a ba owo, ibẹ si ni a o fi si lọ, ẹ ma tori owo gbagbe Ọ l ọ r u n ti o da gbogbo wa o. Lọrọ kan ṣa obinrin yi ti gbagbe iya ti on pẹlu Ọkọ rẹ ti njẹ bọ lati ẹhin wa, o si mu Oruka na lọ fun Ọba laijẹki Ọkọ rẹ mọ ohunkohun nipa rẹ.

Nigbati o ku ọjọ meji ki ọjọ pe, Salimọnu adẹja yi lọ bẹ Oruka yẹn wo, ṣugbọn ko ba ni bẹ mọ, o bere lọwọ Iyawo rẹ, I y ẹ n na sọ fun pe on ko ri. Ha! Ọlọrun ki o gba wa lọwọ aṣe-ni-ba-ni-daro o Amin.

Inu Ọkunrin yi ba jẹ pupọ nigbati ko ri Oruka yi, o si pinnu l a t i lọ ku fun Oruka na. Ṣugbọn ibiti o ti nronu yi ni o ranti Igere ti o dẹ sodo, o si wipe bi on ba tilẹ ma ku on a jẹun ki on to ku ni o ba mura o di bi Igere rẹ, nigbati o debẹ, Igere rẹ pa ẹja mẹrin. Ha! ha! ẹni ti Ọlọrun ko ba ma pa, ko ma ṣeda to

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA

# SURU

## ỌRỌ LORI AW

LATI O

No. 1

Ni igba laila̩i OKunrin Ọ ye ọmọ, Iwọfa, Ẹru; bi o ṣ ni, oruko ekinni a ma jẹ A

Igbesi aiye ọkunrin ọlọrọ yi dun, o s ni arinrin tobẹ ti o jẹ pe gbogbo awọn ara ilu rẹ ni nwọn ma ngbadera ki ara le dẹ a w ọ n na ki aiye awọn na si dun bi tirẹ. Lojojumọ aiye ni ogunlọgọ awọn ọkunrin ati obinrin ma nwọ lọ wọ bọ ninu ile rẹ, a mu para Ọti, ilu a ma dun lọtun losi ninu ile rẹ, gbogbo iyawo rẹ ati awọn ọrẹ a ma yọ ṣẹkẹ. Bi Ọba ilu papa ti to ninu ọla rẹ k o ri ohun iṣura to larin ilu yi, ṣugbọn nigbati to ya bi ẹnyin na ri ṣe mọ wipe kosi nkan ti enia le fi tẹ araiye lọrun. B a y i ni awọn ọta rẹ ba dide si, ni nwọn ba nfi orisirisi ẹsun sun lati ri wipe awọn sa rẹ ọkunrin yi silẹ sa. A mọ sa lẹhin Oninurere ni Ọlọrun

# Awọn Oluwadi niyi

## Enikẹni to ba ni Ọrọ Otitọ lati sọ jẹki o bọ siwaju

IBADAN:- Ọ l ọ l a Dọkita Majekodunmi ti ṣ e Asoju fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Oru, sọ wipe ẹnikẹni o ti n ti awọn ti ijọba gbe si Ahamọ ti o ba ododo ọrọ lati fi han oluwadi ọrọ larapa ohun ti nwọn nṣe iwadi le lori ki o kọwe si Asoju, ki o fi iwe na ran ẹgi ọlọpa ti o nbẹ ni agbegbegbe ibiti o gb e wa ki ilẹ ọjọ keji to mọ nwọn yio si gba laye lati wa sọ tenu rẹ.

## Nwọn yio wa Nibẹ

Ajẹgboro dagba, Olofofo ati Ọgbẹni S. A. Abudu ni yio lọ sibi Iwadi Iwọ Orun ti Ijọba apapọ ti yan Oluwadi si ti yio bẹrẹ l'Eko lojo konkanla oṣu yi l a t i le wa fun yin ni Irohin pẹlu aworan ni orisirisi nipa Iwadi na Nitorina ki olukuluku ẹnyin onkawe wa tọju kọbọ meji yin si itosi.



Ẹniti a nwo yi ni Ọgbẹni B. O. Olowofoyeku, ti o jẹ ọkan ninu Agbẹjọro fun awọn Alstako ninu ọrọ iwadi yi



Ẹniti a nwo yi, ko nṣe Lọya, Ijọba Onisowo, nti awọn ẹgbẹ ti ninu awọn Oluwadi. Oruko rẹ ni o lọ mu Agbeji ninu moto rẹ.

# ...NI IGBEHIN

## ...IYAWO MEJI (Apa Kini)

...ỌLAYIWỌLA AKANDE
...Ọ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

...an ti wa ri, ti o ni ọpọlọpọ ohun ini, si aimọ-
...bogbo nkan wọnyi to, Iyawo meji pere ni o
...ekeji a ma jọ Remi.

...i awọn ba gbera lọ sọ
...ga ibi ti ọkunrin yi
...sisẹ wip "Ọgbẹni ti
...ope ni Oninu-rere ti
... iṣẹ labẹ yin yi, e ko
...ope o ni awọn Ole ti
...ru wa fun ni ile loru
...lupẹlu o nṣe owo ẹda"
...nwọn to sọ fun Ọga
...nwọn awọn Eleri ori-
...ati wa tako, ki Ọlọ-
...a fi gbogbo wa le Ọta
...o, (A m i n). Nigbati
...oniketa yi n'a ṣe gba-
...i nwọn mu Ẹrọ-owo
...ọn ba tun gbe fun
...an ninu ọmọ Ọlọrọ
... ba awọn gbe sinu ile
...awọn ọmọ-ọdọ tun
...iwọn Ọta yi pe awọn
... si wipe ẹrọ owo-ẹda
...ti w i p e o tun ni
... ti o njale fun wa,
...ọio si tọka rẹ si wọn.

O to bi ọsẹ meji ni awọn Ọga ba mu Ọlọpa lati wa wo inu ile rẹ wo, bayi ni wọn ba gbogbo nkan ofin wọnyi ni ile rẹ. Ọlọrọ yi ko mọ bi nkan wọnyi ti ṣe de ile rẹ, ọrọ yi wa su ọkunrin yi to fi jẹ wipe gbogbo nkan ini rẹ lo fi ta tan patapata ti o ba jẹ wipe wọn tete ṣe idajọ fun ni ko ba pọ si ibikan nwọn kan nda ọla fun ti o kan nfi gbogbo owo fun Adajọ lasan. Ọn alara wa ru ganganran fun i d a m u ọkan, ohun ti o ṣe ni lanu ni wipe nigbati o ma fi di oṣu Kẹta gbogbo awọn ọrẹ ti fọn ka mọ loju.



...o si mofin ṣugbọn ori rẹ pe nipa bi awọn
...nawo nipa iṣẹ wọn. Ijọba yan a lati jẹ ọkan
...ni Akintọla williams, on ni a nwo yi nigbati

# Oluwa ni Oluṣọ Aguntan mi

Lati ọwọ:- JOHN FOLORUNSỌ OGUNTOYE
Nọ 3 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye.

Mba sọpe bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le gba mi l a y e lati sọ itan kekere kan sinu iwe rẹ oloyin mọmọ itan na lọ bayi.-

Nigba kan Ọkunrin kan wa ti o jẹ akuṣẹ, Ọkunrin yi kuṣẹ ju ekute ṣọṣi lọ, Orukọ rẹ a ma jẹ Oluwa ni Oluṣọ Aguntan mi.

Ọkunrin kan tun wa ni Ilu yi ti o lowo ti o si tun ni Arẹwa Ọmọbinrin kan.

Ọkunrin Olowo feran Talaka pupọ, yio si ma fun ni owo onjẹ ati aṣọ, Ọkunrin olowo yi wa ṣe Akiyesi wipe ti Ọkunrin Talaka yi ba ti jẹun tan ni yio ma sọ pe Oluwa ni Oluṣọ Aguntan mi, Olowo yi wa pinu lati danwo fun ọrọ ti o ma nsọ yi, o wa di ọjọ kan, o pe Ọkunrin yi o ni ki o ba on toju oruka wura kan o ni ti o ba le mu wa ni nkan bi ọsẹ meji si yio fẹ ọmọ on arẹwa.

Ni Ọkunrin talaka yi ba gba oruka o lọ si Ahere re o lo t ọ j u rẹ sinu iho kekere kan nibẹ.

Nigbati o ṣe olowo yi ba lọ bẹ awọn giripa bi mẹwa wipe ki wọn lọ wa oruka yi wa, o wa fun wọn lowo nigbati o ṣe wọn lọ nigbati wọn de ibẹ wọn wo gbogbo ibiti iho wa nibẹ, wọn ri oruka wọn mu lọ si ọdọ olowo yi nigbati oṣe wọn mu oruka na lọ si ọdọ ti o jin ju ni Ilu yi wọn ju oruka yi sibẹ Ọkunrin olowo si sọ fun Ọkunrin talaka yi pe ko gbọdọ wa si ile on titi on fi ma pe ọkunrin yi si wa owo titi o fi pe kọbọ meji o lọ fi ra akara ati ẹja tutu o pada wa si ahere rẹ. Nigbati o bẹrẹ si jẹun o ṣe Akiyesi pe kini kan ndun ninu ẹja o wa ri wipe oruka wura ti Olowo fun on ki on toju ni, o ya lẹnu pupọ o si sọ pe Oluwa ni Oluṣọ Aguntan mi o tun lọ fi sibomiran ninu Ile rẹ.

Nigbati o di ọjọ keji o pe Ọkunrin yi pe o r u k a naj da ṣugbọn Iyalẹnu lo si jẹ fun Olowo yi pe Ọkunrin talaka yi mu Oruka fun o si tun sọ fun pe Oluwa ni Oluṣọ Aguntan mi o ya Olowo yi lẹnu, o si fi Arẹwa Ọmọ binrin rẹ fun lati fi ṣaya gẹgẹbi adehun tio ti ṣe.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye M. E. R. Okorodudu Q. C. nigbati o tẹ ori bọ ojo ti o nlọ sibi ọrọ iwadi Ijọba Iwọ orun l'Eko.

## Ẹ KU OWURỌ, ẸNYIN ỌMỌDE

Ẹ ku Owurọ, ẹnyin Ọmọde lọkunrin ati lobinrin Alafia kọ ni ẹ wa bi, mo le ro pe gbogbo yin ni o koju mọ ẹkọ rẹ, ẹ maṣe sa ni ile Ẹkọ nitori pe Ojọ nro. (Iṣẹ Ojo ni ojo nṣe) ẹ mu ẹwu Ojo yin ati Bata ki ẹ si sure lọ si ile ẹkọ, nitori iwe ni ogun yin lehin ọla, on ni ẹ o ma jẹ titi aiye, Asiko idanwo yi nsunmọ tosi, ẹ mura lati le yege ninu idanwo na, Ẹ maṣe fi owurọ yin sire.

Mo bẹ ẹnyin Ọmọde, ti ẹ ba nlọ si ile ẹkọ, ti ẹ ba de oju Titi, ẹ ma wo ọna dada ki ẹ to sọda tabi ki ẹ bẹ awọn Agbalagba ti o ba wa nitosi yin ki nwọn mu yin sọda, O l u w a koni jẹki a pade Agbako o.

Ẹnyin Agbalagba, ẹ jọwọ, ẹ ma ran awọn ọmọde lọwọ nipa ti ẹ ba ri wọn ti wọn ba fẹ sọda titi ẹ ma mu wọn sọda, papa ẹnyin Onikẹkẹ, ẹ ma fi ara hale gun kẹkẹ nitosi ibiti awọn ọmọ ile Ẹkọ ba wa, bakanna ẹnyin Awa moto, Oluwa yio ma fi sọ rẹ sọ gbogbo wa Amin. O digba kan na o.

Emi ni ti yin nitọtọ
LATIFU BABALOLA

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

Yẹ irawọ rẹ ti ọsẹ yi wo, kio ba le mọ ibiti iwọ yio gbe ọrọ rẹ gba, nitori ogun agbọtẹlẹ ko npa Arọ

Jan 20-Feb 18 (Aquarius) Ọrọ kan mbọ wa sẹlẹ si ọ, ma ṣe fi wara-wara ja lu ọrọ na, kio ma ba si wa hu, nṣe ni kio wadi ọrọ na kio to da si

Feb 19-Mar 20 (Pisces) Fi gbogbo akoko rẹ ṣiṣẹ ninu ọsẹ yi, ṣugbọn kio fi aṣalẹ ṣe isimi

Mar 21-Apl 19 (Aries) Arisiki rẹ nṣiyemeji lọsẹ yi, ṣugbọn ẹnikan yio ṣe iranlọwọ owo fun ọ yio si ma ran ọ lọwọ nigbagbogbo

Apl 20-May 20 (Turus) Ṣọra rẹ kio ma fi ẹgbọn-riri ba nkan jẹ lọsẹ yi. Ṣugbọn akitiyan rẹ yio pọ, iwọ yio si ba ọpọ enia ṣe ipade

May 21-June 20 (Gemini) Fi gbogbo ọjọ oni ṣe nkan pataki maṣe jafara nipa ọrọ ara rẹ. Tọju ara rẹ kio si simi die

June 21-July 20 (Cancer) Iṣẹ rẹ yio pọ lọsẹ yi, iwọ yio si ṣorire ninu rẹ, inawo rẹ yio pọ, iwọ yio ri owo na

July 21-Aug 22 (Leo) Oju rẹ y o mọ kadara si gbogbo ohun ti o ti nru ọ loju, gbidanwo lati ba awọn enia pataki kẹgbẹ

Aug 23-Sept 22 (Virgo) Tẹ siwaju pẹlu iba owo ti o ni lọwọ iwọ yio si ri ere ẹ nrọlẹ ọjọkan ṣugbọn gbẹkẹle imọ ti Ọlọrun fun ọ

Sept 23-Oct 22 (Libra) Bi o ba fẹ lọ ri enia, akoko asale lo dara fun ọ, ṣugbọn kio fi ọwọ ọrọ mu ọrọ awọn obi rẹ. Ṣọra rẹ lọdọ awọn alayọnusi ati ọrẹ oju

Oct 23-Nov 21 (Scorpio) Ọsẹ yi yio dara fun ọ, bi o ba si gbọn ọsẹ yi yio miringindin fun ọ

Nov 22-Dec 21 (Sagittarius) Bi o ba lọ sọdọ awọn enia nla ti o ṣe pataki lọsẹ yi nkan yio ṣe ẹnure fun ọ tọju awọn nkan rẹ ki nwọn ma ba jilọ

Dec 22-Jan 19 (Capricorn) Gbogbo ọsẹ yi dara fun ọ, iwọ yio si ni ilọsiwaju, gbogbo iṣoro rẹ ni iwọ yio bori.

O BERE LATI OJU EWE KERIN

le pa Oluwarẹ iṣẹ Ọlọrun Oba t o b i, ṣe ri lati igbati Iyawo Ọkunrin yi ti mu oruka yi fun Ọba, ni Ọ b a ti tọju rẹ sinu ọkan ninu Iyara rẹ, ṣugbọn Ọmọ rẹ Agba ṣeṣi wọ iyara na, o ri oruka na nibẹ o si fi si ọwọ laimọ adehun ati ohun gbogbo ti o wa lori oruka na, o bọ si ita o si nṣere kiri, ibiti o ti nrin lọ o de eti odo ti ọkunrin apẹja yi ti npẹja o si pinnu lati wẹ diẹ ki on to pada si ile, o bẹ somi o si bẹrẹ si n w ẹ, ibiti o si ti nwẹ, ni Oruka ọwọ rẹ yọ bọ sinu omi, nigbati o si de ile ko wi ohun kan fun ẹnikẹni, o jẹ wipe ọ k a n ninu awọn ẹja mẹrin ti Ọkunrin yi pa ni o gbe oruka yi mi Ọkunrin yi ta mẹta ninu ẹja na, ọkan ti o si ṣe ku lati jẹ ni o ba oruka yi ninu rẹ. Inu rẹ dun nigbati ọba si ranṣẹ si ki o ba on mu oruka on na wa, o tọwọ bọ apo o mu fun Inu Ọba dun ẹnu si yẹ, ṣugbọn o da Ọkunrin yi lọla o si pin ohun ini rẹ si ọna meji o ko ida kan fun o si fi joye.

Njẹ ẹnyin obinrin ẹ ye ma ro ọkọ yin pin nigbati nkan ba yipada tan ki ẹ si ye ma tu aṣiri ọkọ yin si ita mọ o.

Mo dupẹ lọwọ Olotu Akọwe pupọ fun aye ti wọn gba mi lati fi itan yi si yin leti paapa ẹnyin Ọkunrin ati Obinrin. Njẹ emi Idosu nrele o emi ọmọ aro fọba bẹsun o tun digba kan na o, ki Ọlọrun jẹki a fi ire pade o.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

# RICHALET

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia o si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buburu ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyen ṣe e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn gbogi ba wọnyen a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse, ati ti a w ọ n Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ejẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ. Lakuregbe, orisirisi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ-Iba, arun-Edọki, Aya didun Tanpara ati Ekuru laya

Ara riro, Lapalapa, Egbo-Eṣẹ Amodi Apo Ile itọ, ehin didun tabi ibaradi rıro pẹlu. Egbogi Risalẹti a ma pa gbogbo kokoro buruku ti o wa n i n u ẹjẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara re dajudaju wọ yio ma roh n rẹ fun ẹlomiran p ẹ l u nigbakugba.

Bere lọdọ awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE 22878
WATERLOO MEDICINE STORES
11, FAGBEWESA STREET OSHOGBO.

# Olofofo

LATI QWQ:- Omo "ADE"

Mo ki yin ẹnyin Onkawe mi ẹ ku ilẹ tutu yi, mo si ke si yin ẹ maṣe jẹki o-ogun otutu jinna si yin pẹlu Kọfi gbigbona.

### QRQ IPAYA FUN AWQN IGBIMQ MUSHIN

Bi nwọn ba ni o di owọ Imale, Imale a ni o di ọwọ Qlorun, o ma wa dẹwọ gbogbo ẹnyin Ogunna gbongbo Igbimọ Mushin nitoripe Mushin ti kuro ni Mushin atijọ o si ti di Mushin ti gbogbo awọn enia ngarun wo, ile orişirişi ni o wa ni Mushin nisisiyi, irohin ko to afojuba eni ba de bẹ lo le sọ. Emi Olofofo ko sọ pe ti o ba ti de Gareji-moto ki o sope "şe Mushin ti nwọn npọn na ni yi?" Iwọ ti o ba fẹ mọ daju, wọ ọ lọ siwaju bẹrẹ lati Ladipo, Odu-Abọrẹ, Palm Avenue, iwọ yio ri pe emi OLOFOFO ko fi ọkankan purọ

### ENIA KO GBQDQ FI OWO R'OYI K'OYI MA KQ

Şugbọn ohun abuku pupọ lo si wa ni Mushin ti awọn Ijọba Iwọ-orun tabi awọn Igbimọ ko mojuto pa-a-pa lasiko ojo yi, bata ko ni şe wọ jade nitori ko si Titi Qlọda, afi eyiti awọn Olugbe wọnyi fi ọwọ arawọn şe. Diẹ ninu ohun ti o jẹ abuku Mushin ti emi Olofofo şi lo darukọ ni ọşe yi ni Titi QLQDA ekeji INA LẸNTIRIKI, ẹkẹta OMI ẹkẹrin GAREJI awọn Bọlẹkaja.

Laiko ni awọn ohun ti emi Olofofo darukọ wọnyi emi rope irẹjẹ patapata ni eyi jasi, lẹhin ti awọn Olugbe nşan owo ati wipe owo ori agbegbe ati Mushin ni lati pọ si nişişiyi ju ti atẹhin wa lọ.

Lọdun tokọja ni Oloye S. L. Akintọla ti o wa ni ihamọ nisisiyi leri pe laipẹ jọjọ Ijọba Iwọ Orun yio sọ Muşin di ibode Iwọ Orun şugbọn kilo şe titi doni yi, kaka bẹ ile alagbele mẹwa lo nlọ kọ fun ara rẹ, emi olofofo fi eyi ke si yin, ẹnyin Ijọba Iwọ Orun pe ki ẹ maşe ro pe asiko na yio tun de ti ẹ o ma tan awọn Olugbe Mushin jẹ awọn Olugbe isisiyi ti laju siwaju ati siwaju ni, ko si aye ki ẹnikan tun ma tan wa jẹ mọ, ki o tun ma kole alagbele rẹ wọn ogun ko tun si mọ gbogbo enia lo ti laju paapa nilẹ karọ o jire laiko şe ohun ti a fẹ ẹnyin Oşelu kole ri Ibo wa lo.

### TANI AWQN OLE NA?

Mo ki yin o gbogbo ẹnyin Oşelu, mo tun ki yin ẹnyin Qlọpa lati ori Qga Qlọpa titi de ori awọn Rukurutu Qlọpa.

Ki nto lọ si idalẹ mi lọdun to kọja. mo fi si etigbọ Ijọba Apapọ pe gbogbo ofin ni nwọn nyi pada şugbọn nwọn ko yi ofin awọn Ole pada rara.

Aye tilẹ gba awọn Ole wọnyi to bẹ ti wọn fi ma nfun awọn oni nkan lasiko ti nwọn si ma nfun wọn ni oogun orun sisun pora titi nwọn yio fi şe işẹ ibi wọn tan omitan ngbe moto onimọto wa jale nwọn a si gbe juru si ibiti wọn ba ri.

---

## Eniti ko bimo ri kole mo iyi omo--

# Awure şe suna ọmọ rẹ, o miringindin, o miringindin

EKO:- Irohin koto afojuba ni ti Ikomọjade Qgbẹni Suberu Awure ti o şe ni ọjọ Alaruba ti şe ọjọ Kẹtadinlọgbọn oşu to kọja ninu ile rẹ ni No. 102A Qduufa Street, L'Eko.

Ni dede agogo mẹsan abọ owurọ ọjọ na ni ẹsẹ awọn Alufa ti peşẹ si ile Qgbẹni Awure lati fun ọmọ tuntun na ni Orukọ ni ọna ẹsin Islam, orukọ ti nwọn si fun ọmọ na ni Abudu Salaiman Ayinla. Eyi ni orukọ awọn Alufa ti o şe adura nibi suna na:- Salawu Shomolu, Alhaji Idi-odo Igbaja, Alufa Laolẹ ti Qkinle, Alufa Suberu Akanbi ati awọn gbajumọ Alufa pataki lati Ilọrin.

Nigbati o si di ọsan ọjọ na Baba Sulaimọnu pẹlu iya rẹ ti njẹ Atinukẹ Anikẹ si bẹrẹsi na owo, nigbati o si ma fi to dede agogo meje aşalẹ, ẹsẹ gbogbo awọn ojulumọ Qrẹ ati Ẹbi Baba ọmọ ti peşẹ sinu ile rẹ, nwọn si bẹrẹsi te wọn lọrun nipa onjẹ ati Qti mimu, ti o fi jẹpe ajẹ şẹku ni olukuluku fi onjẹ şe lọjọ na.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa sibi Ikomọ jade na ti aye wa lati darukọ wọn ni:- Alhaji Isọla, Qgbẹni Suberu Akanbi, Musitafa Ajetunbi, Salawu Adinimọjẹ. Kadiri Iyanda, Baba-Lẹmọmu, Durojaye Adebayọ, Garuba Alabi, Adu Ariyọ, Jimọh Akọ, Adebayọ Adisa, Baba Balẹ ati Qgbẹni Omọba F. A. Oyerọgba tişe Akọwe Agba fun Ẹgbẹ Qdọ ti a npe ni Naijiria Youth Pioneers.

Qgbẹni Suberu na sọ fun onirohun wa pe Inu on dun pupọ ni ọjọ na bi o tilẹ jẹ pe ojo nrọ diẹdiẹ nitoripe ero ti pọju bi on ti lero si lọ o si dupẹ pupọ lọwọ awọn ti o wa ibi Ikomọjade na Oluwa ko fi ire na kari gbogbo wa o, Amin.

---

## OWE ILE YORUBA

Lati Qwọ:- MQŞHUDI QLADUNWO
No. 94 Omọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiyẹ

1. Aba mọ ako şe a şe tan o di apọn
2. Aba ni ikan nda, ikan kole la okuta
3. Apani kijẹ ka fi ida kọja ipakọ on
4. Aba ni lorijẹ ile rẹ ni yio ti ma ọbẹ
5. Abanirẹ fi apo ija silẹ
6. Aba ni idi ẹ t i t ọ, ojo ni ki ijẹ kada a
7. Abarapa ti gbogbo enia, okunrin ti ara ẹni

---


GBANGBA DEKUN!! KEDEKE BEWO




OLUBOR EGBOGI "IKQ"

Bi amodi "IKQ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbi-rọbi ko le şe iwoşan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranse ti nwọn npe ni "PORAL" Ojulowo haun-haun, atamatase egbogi fun Ikọ Fere, Ikọ tutu, Ikọ ọna-ọfun, Ikọ igba-aiya, Ikọ-lile, Ikọ ti o ma nmu ki enia ma tu Kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu ki enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL wo, iwọ na yio ri iyatọ ara rẹ ni kiakia. Igba aiya tabi ọna ofun rẹ ti o ma nho yio duro. "IKO" rẹ yio si san patapata, Iwọ yio ma jẹun daradara. Iwọ yio si ma sun fọn-fọn pẹlu alafia ara.

Bere egbogi yi ati awọn orişirişi egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# IWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

# Ajao re Ọrun

## ALAKEJI

Mo ki gbogbo ara Awẹ
Ẹ ma ku irọju o,
Mo ki ara Ọyọ
Ẹ ma ku aṣẹhinde
Ẹ ku i r ọ j n Ọtunba-loye Ajao
Adeniran Opomulero Balogun Ọba
Biku ba polowo, talaka a sunra mọra
Bologbojo ba wọ gbalẹ
Gbogbo mọriwo a dorikodo lawujọ
Iku p'Ajao o polowo ọlọla
Iku pa Balogun o po'ninuro
Agba oke to s'Awẹ di Eko mọ mi kan
Aṣiwaju onigbagbọ to mbẹ latẹbọmi
Ani mo mohun to kọkọ ṣe
Igba Baba kọkọ de lẹ yi
Mo mọ ohun to kọkọ ṣe
Baba fara ṣiṣẹ, o ko sjc jọ
O fi owurọ ṣowo, o bode pade
O bajo rẹ, o baje jẹun
Ani mo mohun to kọkọ ṣe
Igba baba kọkọ de lẹ yi
Mo mohun to kọkọ ṣe
Ogunna gbongbo inu Ẹgbẹ n l a
Igi lẹhin ọgba Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Iku buru ko mọ ẹni ọwọ
Biku ba mọ ẹni ọwọ
Iku ki ba fo Balogun da
Ki ba fọtunba silẹ sile aiye
Ntori ọlọwọ l'Ajao baba re
Baba ayaba ti o nfowo sile so ẹbi ro
Ana kabiyesi to nfi beba run Ẹgbẹ ṣe

İ K U - O! İ K U - O!!

Biku ba gbowo ni
Yeyeṣọrun iba fun ku lowo
Biku gbẹran
Kabiyesi Akurẹ iba ragbo
Ṣugbọn iku ko mẹni ọwọ
Ko ma mẹni a ntiju fun
Ịku to npa akikanju ati akọni
To npa olowo, pa talaka ninu ile
On lo pa Adeniran Ajao
Ọkanṣọṣọ Ajanaku ti nmigbo kiji
Ka to tun rerin o digbo
Ka to rẹfọn o dọdan
Ka to rẹni bi Ajao l'Eko
O dọrun alakeji
Ọrun a dara fun ọ, Baba Adebayọ
Ọrun a yẹ ọ o Balogun

O digba o.

---


## Akiyesi Pataki

### Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!

SENGOVAN TABLETS:- Jẹ Ajidewe egbogi fun awọn agbalagba ati Ilera gẹgẹbi Ọmọkunrin.

SENGOVAN:- jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni Ilu Okere ni Ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti Ilu Western Jarmani fun arẹ a r a cyiti ọjọ ori rọ to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40–80 years).

SENGOVAN jẹ egbogi ti o ti wa lojọ pipẹ fun anfani awọn agbalagba ilu Jarmani ki a to ṣe amuwa rẹ si Ilu Naijiria Ajẹbidan ni ogun yi Irohin ko to afoju ba.

Bere: A o ri lọwọ a w ọ n Oniṣegun (Doctor) Naijiria tabi l ọ w o alagba Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE S T O R E 26, BISHOP STREET LAGOS PHONE: 23745. DIRECTION: 1 to 2 pills sufficient for your constitution, if so do not take more pills at o n e times SENGOVAN IS FOR YOU.


---

# Elewe Taba-Digbolugi fi ponun mẹdogun tanran

EBUTE-METTA:- Ni ọjọ ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kẹfa ọdun yi ni awọn Ọlọpa mu Ọdaran an ti orukọ rẹ njẹ Jimọh Arẹmu ẹni ọdun mẹdọgbọn ti Ọlọpa sọ wipe ko ni ibugbe, wa si iwaju Adajọ Ile Ẹjọ kekere kan ni Ebute-Mẹtta fun ẹ s u n wipe o ko ewetaba-digbolugi (IGBO) sinu apoti rẹ.

Ẹsun ti Ọlọpa ti o mu Ọdaran na ro niwaju Adajọ ni wipe, Ọdaran na ko ewetabi-digbolugi si inu apoti ifalowọ rẹ ni ogunjọ oṣu kẹfa ọdun yi ni opopo Tapa Street ni Ebute-Mẹtta.

Nigbati Ọdaran na rojọ, ti o fi gba wipe on jẹbi, ni Adajọ ba ni kio lo fi ponun mẹdogun (£15) tanran si Kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu-mẹrin jura.

---

# ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE DI ARABA

EKO:- Irohin ko to afojuba niti ere Ariyanjiyan ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ṣe ni ọjọ Satide o ṣ u to kọja yi ni ile Ẹgbẹ No. 42, Bamgboṣe St. L'Eko.

Ero pọ pupọ ti o fi jẹ pe awọn ẹlomiran kori aye joko, o fẹrẹ dabi ẹnipe gbogbo awọn ọmọ Yoruba ni ope sibẹ, ṣugbọn ojuti ni fun awọn ọmọ Ẹgbẹ ti ko wa

Lọṣẹ to mbọ ẹ o ma gbọ ọrọ ti ẹnikan wọn sọ ati iye awọn ti o fi ara mọ AGBẸ ati DỌKITA.

---


Ẹnikẹni ti o ba nfẹ imọran ti ọ daju nipa, gẹgẹbi a ti nṣe ohun ti nwọn npe ni Insurance ki o lọ ri:-

Awọn Ọgbẹni **T. A. BRAITHWAITE (Insurance Brokers) & Co.**

5, Williams Street
P. O. Box 785, Lagos Nigeria.
Telephone 21550, 21559.

Awa ni oniṣowo ti iṣe Aṣoju fun gbogbo awọn Ẹgbẹ oniṣowo Insurance Oriṣiriṣi ni ohun ti a le ṣe Insurance le lori, diẹ ninu wọn ni wọnyi:-

A le fi ẹmi ara ẹni ṣe e.
A le fi dukia ẹni ṣe e.
A le fi mọto ẹni ṣe e.
Ki jamba maṣe ṣelẹ sini.
Ki ma maṣe jo dukia ẹni.
Tabi ki ọkọ ẹni maṣe bajẹ
Gbogbo a w ọ n Oniṣowo Insurance ni a nṣe Aṣoju fun.
Lọfẹ ni a nfi ọna bi a ti nṣe e han awọn to ba fẹ, yio si tẹ Oluwarẹ lọrun

---

## "Agony Of Piles"

Insist always on "CYCLOVEN" the newly discovered preparations for Haemorrhoids-'PILES'-cures at any age whether blind, painful, bleeding portruding. Rectal Iething. Seatworms, Difficult Stool also varicose veins-trouble. Obtainable in Tablets-Ointment-Suppositories of to pieces per packet-Manufactured in Germany-Beware of worthless brands.

STOCKISTS:
Nigerian Medicine Stores, Tinubu Square Lagos.
Commercial Medicine Stores, Zik-Victoria Street Lagos
Adedun Chemists 4, Wakeman Street, Yaba
Alders Pharmacy 69A, Old Yaba Road Ebute-Metta
Waterloo Medicine Stores 8, Palm-Church Street, Lagos
Isẹ Olodumare Dispensary Oke Bola, Ibadan
Ibare Medicine Stores Moshalasi Jimoh, Abeokuta


---

*Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos. Olotu E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odi Aborẹ Mushin.*